

# IRANLỌWỌ LATI OKE

AKOJỌ LATI ỌWỌ WATSON GOODMAN

ỌFẸ — KI IṢE FUN TITA

"IRANLỌWỌ LATI OKE" je akojọ awọn ẹsẹ iwe Mimọ ti o b'aramu nipa ohun ti a nsọrọ le lori ni orişirişi ibi ninu Bibeli. Mo gbagbọ pe iwe àlàyé ti o dara julọ lori iwe Mimọ ni Bibeli fun ara rẹ.

Ọrọ Ọlọrun wa "lati oke" o si jẹ iranlọwọ tõtọ fun awọn ọkan ti ebi npa ti ongbẹ si ngbẹ sipa ododo. Nigbati enia ba ronupiwada, ti o kọ ẹṣẹ silẹ, ti o si pe Jesu Kristi lati gbe nu ọkan rẹ, ti o si fi tọkantọkan rẹ gba Oluwa Jesu Kristi gbọ bi Olugbala, Oluwa yio fi ara Rẹ han fun U, yio si fi ayọ ati Alafia Rẹ fun ọkan onigbagbọ na. Mo ni iriri yi ni ọdun 1937, lati igbana wa emi ko ti ja iṣọkan ti o yanilẹnu yi pẹlu Oluwa. Mo rọ ọ lati fori fun U bi Olugbala ati Oluwa Rẹ NISISIYI, bi iwọ ko ba ti ṣe bẽ.

— Watson Goodman

### Johannu 13:1

Njẹ ki Ajọ-Irekọja ki o to de, nigbati Jesu mọ̀ pe wakati rẹ̀ de tan, ti on ó ti aiye yi kuro lọ sọdọ Baba, fifẹ ti o fẹ awọn tirẹ̀ ti o wà li aiye, o fẹ wọn titi de opin.

### Ifihàn 1:5

Ati lati ọdọ Jesu Kristi, ẹlẹri olõtọ, akọbi ninu awọn okú, ati alaṣẹ awọn ọba aiye. Ẹniti o fẹ wa, ti o si wẹ̀ wa ninu ẹ̀jẹ rẹ̀ kuro ninu ẹ̀ṣẹ wa.

### Jeremiah 31:3

Oluwa ti fi ara hàn fun mi lati okere, pe, Nitõtọ emi fi ifẹni aiyeraiye fẹ ọ, nitorina ni emi ti ṣe pa oreọfẹ mọ fun ọ.

### I Johannu 4:8, 9

Ẹniti kò ba ni ifẹ kò mọ̀ Ọlọrun; nitoripe ifẹ ni Ọlọrun. Nipa eyi li a gbé fi ifẹ Ọlọrun hàn ninu wa, nitoriti Ọlọrun rán Ọmọ bibi rẹ̀ nikanṣoṣo si aiye, ki awa ki o le yè nipasẹ rẹ̀.

### Johannu 3:16

Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẽ gẹ, ti o fi Ọmọ bíbi rẹ̀ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni ìye ainipẹkun.

### Romu 5:8

Ṣugbọn Ọlọrun fi ifẹ On papa si wa hàn ni eyi pe, nigbati awa jẹ ẹlẹṣẹ, Kristi kú fun wa.

# JESU OLORUN ELEDA

### Johannu 1:1, 14

Li àtetekọse li Ọrọ wà, Ọrọ si wà, pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun si li Ọrọ na. . . Ọrọ na si di ara, on si mba wa gbé, (awa si nwò ogo rẹ, ogo bi ti ọmọ bíbi kanṣoṣo lati ọdọ Baba wá,) o kún fun ore-ọfẹ ati otitọ.

### Johannu 14:9, 10

Jesu wi fun u pe, Bi akokò ti mo ba nyin gbé ti pẹ to yi, iwọ kò si ti imọ mi sibẹ Filippi? ẹniti o ba ti ri mi, o ti ri Baba; iwọ ha ti ṣe wipe, Fi Baba hàn wa? Iwọ kò ha gbagbọ pe, Emi wà ninu Baba, ati pe Baba wà ninu mi? ọrọ ti emi nsọ fun nyin, emi kò da a sọ; ṣugbọn Baba ti ngbé inu mi, on ni nṣe iṣẹ rẹ.

### Matteu 1:22, 23

Gbogbo eyi si ṣẹ, ki eyi ti a ti sọ lati ọdọ Oluwa wá li ẹnu woli ki o le ṣẹ, pe, Kiyesi i, wundia kan yio lóyun, yio si bi ọmọkunrin kan, Nwọn o mã pè orukọ rẹ ni Emmanueli, Itumọ eyi ti iṣe, Ọlọrun wà pẹlu wa.

### I Timoteu 3:16

Laiṣiyemeji, titobi ni ohun ijinlẹ ìwa-bi-Ọlọrun, ẹniti a fihan ninu ara, ti a dalare ninu Ẹmí, ti awọn angẹli ri, ti a wasu rẹ larin awọn orilẹ-ede, ti a gbagbọ ninu aiye, ti a gba soke sinu ogo.

### Matteu 8:29

Si wò o, nwọn kigbe soke wipe, Kini ṣe tawa tirẹ, Jesu, iwọ Ọmọ Ọlọrun? iwọ wá lati da wa loro ki o to to akokò?

### I Johannu 4:15

Ẹnikẹni ti o ba jẹwọ pe Jesu Ọmọ Ọlọrun ni, Ọlọrun ngbé inu rẹ, ati on ninu Ọlọrun.

### Kolosse 2:9

Nitoripe ninu rẹ ni gbogbo ẹkún Iwa-Ọlọrun ngbé li araiyara.

### Isaiah 9:6

Nitori a bi ọmọ kan fun wa, a fi ọmọkunrin kan fun wa: ijọba yio si wà li ejika rẹ: a o si ma pe orukọ rẹ ni Iyanu, Oludamòran, Ọlọrun Alagbara, Baba Aiyeraiye, Ọmọ-Alade Alafia.

### Matteu 17:5

Bi o ti nwi lọwọ, wo o, awọsanma didán ṣiji bò wọn: si wo o, ohùn kan lati inu awọsanma wá, ti o wipe, Eyiyi li ayanfẹ Ọmọ mi, ẹniti inu mi dun si gidigidi; ẹ mã gbọ tirẹ.

### Luku 1:35

Angẹli na si dahùn o si wi fun u pe, Ẹmí Mimọ yio tọ ọ wá, ati agbara Ọgá-ogo yio ṣiji bò ọ: nitorina ohun mimọ ti a o ti inu rẹ bi, Ọmọ Ọlọrun li a o ma pè e.

Johannu 13:13

Ẹnyin npè mi li Olukọni ati Oluwa: ẹnyin wi rere; bẹ̃ni mo jẹ.

Johannu 6:35

Jesu wi fun wọn pe, Emi li onjẹ ìye: ẹnikẹni ti o ba tọ̀ mi wá, ebi kì yio pa a; ẹniti o ba si gbà mi gbọ́, orùngbẹ kì yio gbẹ ẹ mọ́ lai.

Johannu 8:58

Jesu si wi fun wọn pe, Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Ki Abrahamu to wà, emi niyi.

Johannu 4:25, 26

Obirin na wi fun u pe, mo mọ̀ pe Messia mbọ̀ wá, ti a npè ni Kristi: nigbati on ba de, yio sọ ohun gbogbo fun wa. Jesu wi fun u pe, Emi ẹniti mba ọ sọ̀rọ yi li on.

Johannu 10:7

Nitorina Jesu tún wi fun wọn pe, Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Emi ni ilẹkun awọn agutan.

Johannu 11:25

Jesu wi fun u pe, Emi ni ajinde, ati ìye: ẹniti o ba gbà mi gbọ́, bi o tilẹ kú, yio yè.

Johannu 9:5

Niwọn igba ti mo wà li aiye, emi ni imọlẹ aiye.

Johannu 8:23

O si wi fun wọn pe, Ẹnyin ti isalẹ wá; emi ti oke wá: ẹnyin jẹ ti aiye yi; emi kì iṣe ti aiye yi.

### Luku 5:4-6

Bi o si ti dakẹ ọ́rọ isọ, o wi fun Simone pe, Ti si ibu, ki o si ju áwon nyin si isalẹ fun akopọ̀. Simoni si dahùn o si wi fun u pe, Olukọni, gbogbo oru aná li awa fi ṣiṣẹ, awa kò si mú nkan: ṣugbọn nitori ọrọ re emi ó jù àwọn na si isalẹ. Nigbati nwọn ṣi ti se eyi, nwọn kó ọpọlọpọ ẹja: àwọn wọn si ya.

### Matteu 14:19-21

O si paṣẹ ki ijọ enia joko lori koriko, o si mu iṣu akara marun ati ẹja meji na; nigbati o gbé oju soke ọrun, o sure, o si bù u, o fi akara na fun awọn ọmọ-ẹhin rè, awọn ọmọ-ẹhin rẹ si fifun ijọ enia. Gbogbo nwọn si jẹ, nwọn si yó; nwọn si ko ajẹkù ti o kù jọ, agbọ̀n mejila kún. Awọn ti o si jẹ ẹ to ìwọn ẹgbẽdọgbọn ọkunrin, li aikà awọn obirin ati awọn ọmọde.

### Matteu 20:30, 34

Si kiyesi i, awọn ọkunrin afọju meji joko leti ọ̀na; nigbati nwọn gbọ́ pe Jesu nrekọja, nwọn kigbe soke, wipe, Oluwa, iwọ Ọmọ Dafidi, ṣãnu fun wa. . . Bẽni Jesu ṣãnu fun wọn, o si fi ọwọ́ tọ́ wọn li oju: ọgan oju wọn si là, nwọn si tọ̀ ọ lẹhin.

### Romu 14:9

Nitori idi eyi na ni Kristi ṣe kú, ti o si tún yè, ki o le jẹ Oluwa ati okú ati alãye.

### Heberu 1:2

Ọlọrun. . . ni ikẹhin ọjọ wọny o ti ipasẹ Ọmọ rẹ ba wa sọ̀rọ, ẹniti o fi ṣe ajogun ohun gbogbo, nipasẹ ẹniti o dá awọn aiye pẹlu.

### Johannu 1:3

Nipasẹ̀ rẹ li a ti da ohun gbogbo; lẹhin rẹ̀ a ko si da ohun kan ninu ohun ti a da.

### Kolosse 1:16

Nitori ninu rẹ̀ li a ti dá ohun gbogbo, ohun ti mbẹ li ọrun, ati ohun ti mbẹ li aiye, eyiti a ri, ati eyiti a kò ri, nwọn iba ṣe itẹ̀, tabi oye, tabi ijọba, tabi ọla: nipaṣẹ rẹ̀ li a ti dá ohun gbogbo, ati fun u.

### I Korinti 1:9

Olododo li Ọlọrun, nipasẹ ẹniti a pè nyin sinu idapọ Ọmọ rẹ̀ Jesu Kristi Oluwa wa.

### Efesu 3:9

Ati lati mu ki gbogbo enia ri kini iṣẹiriju ohun ijinlẹ na jasi, eyiti a ti fi pamọ́ lati aiyebaiye ninu Ọlọrun, ẹniti o dá ohun gbogbo nipa Jesu Kristi.

### Iṣe 2:36

Njẹ ki gbogbo ile Israeli ki o mọ̀ dajudaju pe, Ọlọrun ti fi Jesu na, ti ẹnyin kàn mọ agbelebu jẹ Oluwa ati Kristi.

Iṣe 10:42

O si paṣẹ fun wa lati wasu fun awọn enia, ati lati jẹri pe, on li a ti ọwọ Ọlọrun yàn ṣe Onidajọ ãye on okú.

Matteu 25:32

Niwaju rẹ li a o si kó gbogbo orilẹ-ède jọ: yio si yà wọn si ọtọ kuro ninu ara wọn, gẹgẹ bi oluṣọ-agutan ti iyà agutan rẹ kuro ninu ewurẹ.

Johannu 5:22

Nitoripe Baba ki iṣe idajọ ẹnikẹni, ṣugbọn o ti fi gbogbo idajọ le Ọmọ lọwọ.

Romu 14:10

Ṣugbọn ẽṣe ti iwọ fi nda arakunrin rẹ lẹjọ? tabi ẽsitiṣe ti iwọ fi nkẹgan arakunrin re? gbogbo wa ni yio sá duro niwaju itẹ idajọ Kristi.

Romu 2:16

Li ọjọ na nigbati Ọlọrun yio ti ipa Jesu Kristi ṣe idajọ aṣiri enia gẹgẹ bi ihinrere mi.

Luku 3:17

Ẹniti atẹ rẹ mbẹ li ọwọ rẹ, lati gbá ilẹ ipaka rẹ mọ toto, ki o si kó alikama rẹ sinu aká; ṣugbọn iyangbo ni yio fi iná ajõku sun.

II Timoteu 4:1

Nitorina mo paṣẹ fun ọ niwaju Ọlọrun, ati Kristi Jesu, ẹniti yio ṣe idajọ alãye ati okú, ati nitori ifarahàn rẹ ati ijọba rẹ.

**Heberu 5:9**

Bi a si ti sọ ọ di pipé, o wá di orisun igbala ainipẹkun fun gbogbo awọn ti o ngbọ́ tirẹ̀.

**Johannu 10:9**

Emi ni ilẹkun: bi ẹnikan ba ba ọdọ mi wọle, on li a o gbà là, yio wọle, yio si jade, yio si ri koriko.

**Johannu 14:6**

Jesu wi fun u pe, Emi li ọna, ati otitọ, ati iye: kò si ẹnikẹni ti o le wá sọdọ Baba, bikoṣe nipasẹ mi.

**Iṣe 4:12**

Kò si si igbala lọdọ ẹlomiran: nitori kò si orukọ miran labẹ ọrun ti a fifunni ninu enia, nipa eyiti a le fi gbà wa là.

**Heberu 7:25**

Nitorina o si le gba wọn là pẹlu titi de opin, ẹniti o ba tọ̀ Ọlọrun wá nipasẹ rẹ̀, nitoriti o mbẹ lãye titi lai lati mã bẹ̀bẹ fun wọn.

**Johannu 8:24**

Nitorina ni mo ṣe wi fun nyin pe, ẹ ó kú ninu ẹ̀ṣẹ nyin: nitori bikoṣe ẹ ba gbagbọ́ pe, emi ni, ẹ ó kú ninu ẹ̀ṣẹ nyin.

**I Tessalonika 5:9**

Nitori Ọlọrun yàn wa ki iṣe si ibinu, ṣugbọn si ati ni igbala nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa.

### Kolosse 1:12-14

Ki a mã dupẹ lọwọ Baba, ẹniti o mu wa yẹ lati jẹ alabapin ninu ogún awọn enia mimọ́ ninu imọlẹ: ẹniti o ti gbà wa kuro lọwọ agbara òkunkun, ti o si ṣi wa nipo sinu ijọba ayanfẹ Ọmọ rẹ̀: ninu ẹniti awa ni idande nipa ẹ̀jẹ rẹ̀, ani idariji ẹ̀ṣẹ.

### I Korinti 1:30

Ṣugbọn nipasẹ rẹ̀ li ẹnyin wà ninu Kristi Jesu, ẹniti Ọlọrun fi ṣe ọgbọ́n, ati ododo, ati isọdimimọ́, ati idande fun wa.

### Ifihàn 5:9

Nwọn si nkọ orin titun kan, wipe, Iwọ li o yẹ lati gbà iwe na, ati lati ṣí èdidi rẹ̀: Nitoriti a ti pa ọ, iwọ si ti fi ẹ̀jẹ rẹ ṣe ìrapada enia si Ọlọrun Lati inu ẹyà gbogbo, ati ède gbogbo, ati enia gbogbo, ati orilẹ-ède gbogbo wá.

### Luku 19:10

Nitori Ọmọ-enia de lati wà awọn ti o nù kiri, ati lati gbà wọn là.

### Romu 3:24

Awọn ẹniti a ndalare lọfẹ nipa ore-ọfẹ rẹ̀, nipa idande ti o wà ninu Kristi Jesu.

### Titu 2:14

Ẹniti o fi ara rẹ̀ fun wa, ki on ki o le rà wa pada kuro ninu ẹ̀ṣẹ gbogbo, ki o si le wẹ awọn enia kan mọ́ fun ara rẹ̀ fun ini on tikalarẹ awọn onitara iṣẹ rere.

### Matteu 26:28

Nitori eyi li ẹ̀jẹ mi ti majẹmu titun, ti a ta silẹ fun ọ̀pọ enia fun imukuro ẹ̀ṣẹ.

### Romu 5:9

Melomelo si ni, ti a da wa lare nisisiyi nipa ẹ̀jẹ rẹ̀, li a o gbà wa là kuro ninu ibinu nipasẹ rẹ̀.

### Efesu 1:7

Ninu ẹniti awa ni irapada wa nipa ẹ̀jẹ rẹ̀, idariji ẹ̀ṣẹ wa, gẹgẹ bi ọrọ̀ ore-ọfẹ rẹ̀.

### I Peteru 1:18, 19

Niwọnbi ẹnyin ti mọ̀ pe, a kò fi ohun ti idibajẹ, rà nyin pada, bi fadaka tabi wura, kuro ninu ìwa asan nyin, ti ẹnyin ti jogun lati ọdọ awọn baba nyin, bikoṣe ẹ̀jẹ iyebiye, bi ti ọdọ-agutan ti kò li abuku, ti kò si li abawọn, ani ẹ̀jẹ Kristi.

### Heberu 9:14

Melomelo li ẹ̀jẹ Kristi, ẹni nipa Ẹmí aiyeraiye ti o fi ara rẹ̀ rubọ si Ọlọrun li aini àbawọn, yio wẹ̀ eri-ọkàn nyin mọ́ kuro ninu okú ẹṣẹ lati sìn Ọlọrun alãye?

### I Johannu 1:7

Ṣugbọn bi awa ba nrìn ninu imọlẹ, bi on ti mbẹ ninu imọlẹ, awa ní ìdapọ pẹlu ara wa, ẹ̀jẹ Jesu Kristi Ọmọ rẹ̀ ni nwẹ̀ wa nù kuro ninu ẹṣẹ gbogbo.

**I Johannu 5:4**

Nitori olukuluku ẹniti a bí nipa ti Ọlọrun o ṣẹgun aiye: eyi si ni iṣẹgun ti o ṣẹgun aiye, ani igbagbọ wa.

**Efesu 2:8, 9**

Nitori ore-ọfẹ li a ti fi gbà nyin là nipa igbagbọ; ati eyini kì iṣe ti ẹnyin tikaranyin: èbun Ọlọrun ni: kì iṣe nipa iṣẹ ki ẹnikẹni má bã ṣogo.

**Johannu 6:28, 29**

Nigbana ni nwọn wi fun u pe, Kili awa o ha ṣe, ki a le ṣe iṣẹ Ọlọrun? Jesu dahùn o si wi fun wọn pe, Eyi ni iṣẹ Ọlọrun pe, ki ẹnyin ki o gbà ẹniti o rán gbọ.

**Johannu 20:31**

Ṣugbọn wọnyi li a kọ, ki ẹnyin ki o le gbagbọ pe, Jesu ni iṣe Kristi na, Ọmọ Ọlọrun; ati ni gbigbàgbọ, ki ẹnyin ki o le ni ìye li orukọ rẹ.

**Filippi 3:9**

Ki a si le bá mi ninu rẹ, li aini ododo ti emi tikarami, ti o ti inu ofin wá, ṣugbọn eyi ti o ti inu igbagbọ wá ninu Kristi, ododo ti Ọlọrun nipasẹ igbagbọ.

**Romu 5:1**

Njẹ bi a si ti nda wa lare nipa igbagbọ, awa ni alafia lọdọ Ọlọrun nipa Oluwa wa Jesu Kristi.

**Orin 103:11**

Nitoripe, bi ọrun ti ga si ilẹ, Bẽli ãnu rẹ̀ tobi si awọn ti o bẹ̀ru rẹ̀.

**Orin 103:17**

Ṣugbọn ãnu Oluwa lati aiyeraiye ni lara awọn ti o bẹ̀ru rẹ̀.

**Titu 3:5**

Kì iṣe nipa iṣẹ ti awa ṣe ninu ododo ṣugbọn gẹgẹ bi ãnu rẹ̀ li o gbà wa là, nipa ìwẹnu atúnbi ati isọdi titun Ẹmí Mimọ́.

**Mika 7:18**

Tani Ọlọrun bi iwọ, ti o ndari aiṣedede jì, ti o si ndiju si ẹṣẹ awọn iyoku ini rẹ̀? kò dá ibinu rẹ̀ duro titi lai, nitori on ni inudidun si ãnu.

**I Peteru 1:3**

Olubukún li Ọlọrun ati Baba Jesu Kristi Oluwa wa, Ẹniti o tún wa bi, gẹgẹ bi ọ̀pọlọpọ ãnu rẹ̀, sinu ireti ãye nipa ajinde Jesu Kristi kuro ninu okú.

**Ẹkún 3:22, 23**

Ãnu Oluwa ni ti awa kò parun tan, nitori irọnu-ãnu rẹ kò li opin; Ọtun ni li orowurọ; titobi ni otitọ rẹ.

**Orin 108:4**

Nitoriti ãnu rẹ tobi jù ọrun lọ: Ati otitọ rẹ si de awọsanma.

### Ifihàn 22:17

Ati Ẹmí ati iyawo wipe, Mã bọ̀. Ati ẹniti o ngbọ́ ki o wipe, Mã bọ̀. Ati ẹniti ongbẹ ngbẹ ki o wá. Ẹnikẹni ti o ba si fẹ, ki o gbà omi ìye na lọfẹ.

### Isaiah 55:1

Njẹ gbogbo ẹniti ongbẹ ngbẹ, ẹ wá sibi omi; ati ẹniti kò li owo, ẹ wá, ẹ rà, ki ẹ si jẹ; lõtọ ẹ wá, ẹ rà ọti-waini ati wàra, laini owo ati laidiyele.

### Isaiah 1:18

Oluwa wipe, wá nisisiyi, ki ẹ si jẹ ki a sọ asọyé pọ̀: bi èṣẹ nyin ba ri bi òdodó, nwọn o si fun bi ẹgbọn owu; bi nwọn pọ́n bi àlãri, nwọn ó dabi irunagutan.

### Johannu 7:37

Lọjọ ikẹhìn, ti iṣe ọjọ nla ajọ, Jesu duro, o si kigbe, wipe, Bi òrùngbẹ ba ngbẹ ẹnikẹni, ki o tọ mi wá, ki o si mu.

### Genesisi 7:1

Oluwa si wi fun Noa pe, iwọ wá, ati gbogbo awọn ara ile rẹ sinu ọkọ̀, nitori iwọ ni mo ri li olododo niwaju mi ni iran yi.

### Matteu 11:28

Ẹ wá sọdọ mi gbogbo ẹnyin ti nṣiṣẹ, ti a si di ẹrù wuwo le lori, emi o si fi isimi fun nyin.

**I Johannu 3:10**

Ninu eyi li awọn ọmọ Ọlọrun nfarahan, ati awọn ọmọ Èṣu: ẹnikẹni ti kò ba nṣe ododo kì iṣe ti Ọlọrun, ati ẹniti kò fẹràn arakunrin rẹ.

**Johannu 1:12**

Ṣugbọn iye awọn ti o gbà a, awọn li o fi agbara fun lati di ọmọ Ọlọrun, ani awọn na ti o gbà orukọ rẹ gbọ́.

**II Korinti 6:17, 18**

Nitorina ẹ jade kuro larin wọn, Ki ẹ si yà ara nyin si ọtọ, Li Oluwa wi, Ki ẹ máṣe fi ọwọ́ kàn ohun aimọ́; Emi o si gbà nyin. Emi o si jẹ Baba fun nyin, Ẹnyin o si jẹ ọmọkunrin mi ati ọmọbirin mi, Li Oluwa Olodumare wi.

**Romu 8:14, 15**

Nitori iye awọn ti a nṣe amọ̀na fun lati ọdọ Ẹmí Ọlọrun wá, awọn ni iṣe ọmọ Ọlọrun. Nitori ẹnyin kò tun gbà ẹmí ẹrú lati mã bẹru mọ́: ṣugbọn ẹnyin ti gbà ẹmí isọdọmọ, nipa eyi ti awa fi nke pè, Abba, Baba.

**Filippi 2:15**

Ki ẹnyin ki o le jẹ alailẹgàn ati oniwa tutu, ọmọ Ọlọrun, alailabawọn, larin oniwà wíwọ ati alarekereke orilẹede, larin awọn ẹniti a nri nyin bi imọlẹ li aiye.

### Galatia 5:19-21

Nję awọn isẹ ti ara farahàn, ti iṣe wọnyi; panṣaga, àgbere, ìwa-ẽri, wọ̀bia, ìbọriṣa, oṣó, irira, ìja, ilara, ibinu, asọ, ìṣọtẹ, adamọ̀, arankàn, ìpania, imọtipara, irédeoru, ati iru wọnni: awọn ohun ti mo nwi fun nyin tẹlẹ, gẹgẹ bi mo ti wi fun nyin tẹlẹ rí pe, awọn ti nṣe nkan bawọnni kì yio jogún ijọba Ọlọrun.

### Owe 20:1

Ẹlẹya li ọti-waini, alariwo li ọti lile; Ẹnikẹni ti a ba fi tanjẹ kò gbọ́n.

### Isaiah 5:11

Egbe ni fun awọn ti ima dide ni kùtukutu, ki nwọn le ma lepa ọti lile; ti nwọn wà ninu rẹ̀ titi di alẹ, titi ọtiwaini mu ara wọn gbona!

### Romu 13:13, 14

Jẹ ki a mã rìn ìrin titọ, bi li ọsán; kì iṣe ni irédeoru ati ni imọtipara, kì iṣe ni iwa-ẽri ati wọbia, kì iṣe ni ìja ati ilara. Ṣugbọn ẹ gbe Jesu Kristi Oluwa wọ̀, ki ẹ má si pèse fun ara, lati mã mu ifẹkufẹ rẹ̀ ṣẹ.

### Owe 23:31, 32

Iwọ máṣe wò ọti-waini pe o pọn, Nigbati o ba fi àwọ rẹ̀ han ninu ago, Ti a ngbe e mì, ti o ndùn. Nikẹhin on a bunisán bi ejò, A si bunijẹ bi paramọlẹ.

### Matteu 22:37, 38

Jesu si wi fun u pe, Ki iwọ ki o fi gbogbo àiya rẹ, at i gbogbo ọkàn rẹ, ati gbogbo inu rẹ, fẹ Ọlọrun Oluwa rẹ. Eyi li ekini ati ofin nla.

### Marku 10:17-22

Bi o si ti njade bọ̀ si ọ̀na, ẹnikan nsare tọ̀ ọ wá, o si kunlẹ fun u, o bi i lẽre, wipe, Olukọni rere, kili emi o ṣe ti emi o fi le jogún ìye ainipẹkun? Jesu si wi fun u pe, Ẽṣe ti iwọ fi npè mi li ẹni rere? ẹni rere kan ko si bikoṣe ẹnikan, eyini li Ọlọrun. Iwọ sá mọ̀ ofin: Máṣe panṣaga, Máṣe pania, Máṣe jale, Máṣe jẹri eke, Máṣe rẹ-ni-jẹ, Bọwọ fun baba on iya rẹ. O si dahùn o si wi fun u pe, Olukọni, gbogbo nkan wọnyi li emi ti nkiyesi lati igba ewe mi wá. Nigbana ni Jesu sì wò o, o fẹràn rẹ̀, o si wi fun u pe, Ohun kan li o kù ọ kù: lọ, tà ohunkohun ti o ni ki o si fifun awọn talakà, iwọ ó si ni iṣura li ọrun: si wá, gbé agbelebu, ki o si mã tọ̀ mi lẹhin. Inu rẹ̀ si bajẹ si ọ̀rọ̀ na, o si jade lọ ni ibinujẹ: nitoriti o li ọrọ̀ pipọ.

### Owe 16:25

Ọ̀na kan wà ti o dabi ẹnipe o dara fun enia, Ṣugbọn opin rẹ̀ li ọ̀na ikú.

### I Johannu 3:7, 8a

Ẹnyin ọmọ mi, ẹ máṣe jẹ ki ẹnikẹni ki o tàn nyin: ẹniti o ba nṣe ododo, o jasi olododo, gẹgẹ bi on ti iṣe olododo. Ẹniti o ba ndẹṣẹ ti Èṣu ni; nitori lati àtetekọṣe ni Èṣu ti ndẹṣẹ.

### Jakọbu 1:22

Ṣugbọn ki ẹ jẹ oluṣe ọ̀rọ na, ki o má si ṣe olugbọ́ nikan, ki ẹ ma tàn ara nyin jẹ.

### I Korinti 6:9, 10

Ẹnyin kò mọ̀ pe awọn alaiṣõtọ kì yio jogún ijọba Ọlọrun? Ki a má tàn nyin jẹ: kì iṣe awọn àgbere, tabi awọn abọriṣa, tabi awọn panṣaga, tabi awọn alailera, tabi awọn ti nfi ọkunrin bà ara wọn jẹ́, tabi awọn olè, tabi awọn olojukòkoro, tabi awọn ọmuti, tabi awọn ẹlẹgàn, tabi awọn alọnilọwọgbà ni yio jogún ijọba Ọlọrun.

### Galatia 6:3

Nitori bi enia kan ba nrò ara rẹ̀ si ẹnikan, nigbati kò jẹ nkan, o ntàn ara rẹ̀ jẹ.

### Efesu 5:6

Ẹ máṣe jẹ ki ẹnikẹni fi ọ̀rọ asan tàn nyin jẹ: nitori nipasẹ nkan wọnyi ibinu Ọlọrun mbọ̀ wá sori awọn ọmọ alaigbọran.

### Luku 15:32

O yẹ ki a ṣe ariya ki a si yọ: nitori aburo rẹ yi ti kú, o si tún yè; o ti nù, a si ri i.

### Owe 11:19

Bi ẹniti o duro ninu ododo ti iní ìye, Bẽni ẹniti nlepa ibi, o nle e si ikú ara rẹ.

### Romu 8:6, 7

Nitori ero ti ara ikú ni; ṣugbọn ero ti Ẹmí ni iye ati alafia: nitori ero ti ara ọtá ni si Ọlọrun: nitori ki itẹriba fun ofin Ọlọrun, on kò tilẹ le ṣe e.

### Esekieli 18:20

Ọkàn ti o ba ṣẹ, on o kú. Ọmọ kì yio rù aiṣedẽde baba, bẽni baba kì yio rù aiṣedẽde ọmọ: ododo olododo yio wà lori rẹ, ìwa buburu enia buburu yio si wà lori rẹ.

### Romu 6:21

Njẹ eso kili ẹnyin ha ni nigbana ninu ohun ti oju ntì nyin si nisisiyi? nitori opin nkan wọnni ikú ni.

### Romu 5:12

Nitori gẹgẹ bi ẹṣẹ ti ti ipa ọdọ enia kan wọ aiye, ati ikú nipa ẹṣẹ; bẽni ikú si kọja sori enia gbogbo, lati ọdọ ẹniti gbogbo enia ti dẹṣẹ.

### Jakọbu 1:15

Njẹ, ifẹkufẹ na nigbati o ba lóyun, a bí ẹṣẹ: ati ẹṣẹ na nigbati o ba si dagba tan, a bí ikú.

### Johannu 11:43, 44

Nigbati o si ti wi bẽ tan, o kigbe li ohùn rara pe, Lasaru, jade wá. Ẹniti o kú na si jade wá, ti a fi aṣọ okú dì tọwọ tẹsẹ a si fi gèle dì i loju. Jesu wi fun wọn pe, Ẹ tú u, ẹ si jẹ ki o mã lọ.

### Ifihàn 1:18

Emi li ẹniti o mbẹ lãye, ti o si ti kú; si kiyesi i, emi si mbẹ lãye si i titi lai, Amin; mo si ni kọkọrọ ikú ati ti ipo-oku.

### Johannu 10:17, 18

Nitorina ni Baba mi ṣe fẹran mi, nitoriti mo fi ẹmí mi lelẹ, ki emi ki o le tún gbà a. Ẹnikan kò gbà a lọwọ mi, ṣugbọn mo fi i lelẹ fun ara mi. Mo li agbara lati fi i lelẹ, mo si li agbara lati tun gbà a. Aṣẹ yi ni mo ti gbà lati ọdọ Baba mi wá.

### I Korinti 15:3, 4

Nitoripe ṣiwaju ohun gbogbo mo fi eyiti emi pẹlu ti gbà le nyin lọwọ, bi Kristi ti kú nitori ẹṣẹ wa gẹgẹ bi iwemimọ ti wi; ati pe a sinkú rẹ, ati pe o jinde ni ijọ kẹta gẹgẹ bi iwemimọ ti wi.

### Luku 7:14, 15a

O si wá, o si fi ọwọ tọ aga posi na: awọn ti si nrù u duro jẹ. O si wipe, Ọdọmọkunrin, mo wi fun ọ, Dide. Ẹniti o kú na si dide joko, o bẹrẹ si ohùn ifọ. . .

### Deuteronomi 5:7-21

Iwọ kò gbọdọ ni ọlọrun miran pẹlu mi.

Iwọ kò gbọdọ yá ere fun ara rẹ, tabi aworán apẹrẹ kan ti mbẹ loke ọrun, tabi ti mbẹ ni ilẹ nisalẹ, tabi ti mbẹ ninu omi ni isalẹ ilẹ: iwọ kò gbọdọ tè ori rẹ ba fun wọn, bẽni iwọ kò gbọdọ sìn wọn. . .

Iwọ kò gbọdọ pẹ orukọ OLUWA Ọlọrun rẹ li asan: nitoriti OLUWA kọ ni yio mu ẹniti o pè orukọ rẹ li asan bi alailẹṣẹ lọrùn.

Kiyesi ọjọ-isimi lati yà a si mimọ, bi OLUWA Ọlọrun rẹ ti paṣẹ fun ọ: ijọ mẹfa ni iwọ o ṣiṣẹ, ti iwọ o si ṣe iṣẹ rẹ gbogbo: ṣugbọn ọjọ keje li ọjọ-isimi OLUWA Ọlọrun rẹ. . .

Bòwọ fun baba ati iya rẹ, bi OLUWA Ọlọrun rẹ ti páṣẹ fun ọ.

Iwọ kò gbọdọ pania.

Bẽni iwọ kò gbọdọ ṣe panṣaga.

Bẽni iwọ kò gbọdọ jale.

Bẽni iwọ kò gbọdọ jẹri-eké si ẹnikeji rẹ.

Bẽni iwọ kò gbọdọ ṣojukokoro si aya ẹnikeji rẹ; bẽni iwọ kò gbọdọ ṣojukokoro si ile ẹnikeji rẹ, oko rẹ, ati ọmọ-ọdọ rẹ ọkunrin, ati ọmọ-ọdọ rẹ obirin, akọmalu rẹ, ati kẹtẹkẹtẹ rẹ, ati ohun gbogbo ti iṣe ti ẹnikeji rẹ.

## Jobu 34:21, 22

Nitoripe oju rè mbẹ ni ipa-ọ̀na enia, On si ri irin rè gbogbo. Kò si òkunkun, tabi ojiji ikú, Nibiti awọn onisẹ ẹ̀sẹ yio gbe sapamọ si.

## Luku 8:17

Nitori kò si ohun ti o lumọ́, ti a ki yio fi hàn, bẹ̃ni kò si ohun ti o pamọ́, ti a kì yio mọ̀ ti ki yio si yọ si gbangba.

## Orin 139:8, 12

Bi emi ba gòke lọ si ọrun, iwọ wà nibẹ: Bi emi ba si tẹ́ ẹni mi ni ipò-okú, kiyesi i, iwọ wà nibẹ. . . Nitõtọ òkunkun kì işú lọdọ rẹ; Şugbọn oru tàn imọlẹ bi ọsan: Ati òkunkun ati imọlẹ, mejeji bakanna ni fun ọ.

## Owe 15:3

Oju Oluwa mbẹ ni ibi gbogbo; O nwò awọn ẹni-buburu ati ẹnirere.

## Işe 17:27

Ki nwọn ki o le mã wá Oluwa, bọya bi ọkàn wọn ba le fà si i, ti wọn si ri i, bi o tilẹ şe pe kò jina si olukuluku wa.

## Jeremiah 23:24

Enikẹni le fi ara rè pamọ ni ibi ikọkọ, ti emi kì yio ri i? li Oluwa wi. Emi kò ha kún ọrun on aiye? li Oluwa wi.

# IYA AINIPẸKUN WA FUN' AWỌN ALAIWABI ỌLỌRUN

## Orin 9:17

Ori awọn enia buburu li a o dà si ọrun apadi, Ati gbogbo ori-lẹ-ède ti o gbagbe Ọlọrun.

## Matteu 25:46

Awọn wọnyi ni yio si kọja lọ sinu ìya ainipẹkun: ṣugbọn awọn olõtọ si ìye ainipẹkun.

## Ifihàn 20:15

Bi a ba si ri ẹnikẹni ti a kò kọ orukọ rè sinu iwe ìye, a sọ ọ sinu adagun iná.

## Matteu 13:41, 42

Ọmọ-enia yio rán awọn angẹli rẹ, nwọn o si kó gbogbo ohun ti o mu-ni-kọsè ni ijọba rẹ kuro, ati awọn ti o ndẹṣẹ. Yio si sọ wọn sinu iná ileru: nibẹ li ẹkún on ipanhinkeke yio gbe wà.

## II Peteru 3:7

Ṣugbọn awọn ọrun ati aiye, ti mbẹ nisisiyi, nipa òrọ kanna li a ti tojọ bi iṣura fun iná, a pa wọn mọ dè ọjọ idajọ ati iparun awọn alaiwa-bi-Ọlọrun.

## Matteu 18:8

Bi ọwọ rẹ tabi ẹsẹ rẹ ba si mu ọ kọsè, ke e kuro, ki o si sọ ọ nù; o sàn fun o ki ọ ṣe akewọ, tabí akesẹ lọ sinu ìye, jù ki o li ọwọ meji tabi ẹsẹ meji, ki a gbé ọ jù sinu iná ainipẹkun.

## II Peteru 2:9

Oluwa mọ̀ bi ã ti íyọ awọn ẹni ìwa-bi-Ọlọrun kuro ninu idanwo, ati bi ã ti ípa awọn alaiṣõtọ ti a nję niya mọ dè ọjọ idajọ.

## Heberu 9:27

Niwọn bi a si ti fi lelę fun gbogbo enia lati kú lẽkanṣoṣo, ṣugbọn lẹhin eyi idajọ.

## Iṣe 17:31

Niwọnbi o ti da ọjọ kan, ninu eyi ti yio ṣe idajọ aiye li ododo, nipasẹ ọkunrin na ti o ti yàn, nigbati o ti fi ohun idaniloju fun gbogbo enia, niti o jí i dide kuro ninu okú.

## Romu 14:12

Njẹ nitorina, olukuluku wa ni yio jihin ara rẹ̀ fun Ọlọrun.

## II Korinti 5:10

Nitoripe gbogbo wa kò le ṣai-ma fi ara hàn niwaju itẹ́ idajọ Kristi; ki olukuluku ki o le gbà nkan wọnni ti o ṣe ninu ara gẹgẹ bi eyi ti o ti ṣe, ibã ṣe, rere ibã ṣe buburu.

## I Johannu 4:17

Ninu eyi li a mu ifẹ ti o wà ninu wa pé, ki awa ki o le ni igboiya li ọjọ idajọ: nitoripe bi on ti ri, bẽli awa si ri li aiye yi.

### II Korinti 9:15
Ọpẹ ni fun Ọlọrun nitori alaileso èbun rẹ.

### II Korinti 8:9
Nitori ẹnyin mọ ore-ọfẹ Oluwa wa Jesu Kristi, pe bi on ti jẹ ọlọrọ rí, ṣugbọn nitori nyin o di talaka, ki a le sọ nyin di ọlọrọ nipa aini rẹ.

### Romu 9:16
Njẹ bẽni kì iṣe ti ẹniti o fẹ, kì si iṣe ti ẹniti nsáre, bikoṣe ti Ọlọrun ti nṣãnu.

### Romu 5:15
Ṣugbọn kì iṣe bi ẹ̀ṣẹ bẽ si li ẹ̀bun ọfẹ. Nitori bi nipa ẹ̀ṣẹ ẹnikan, ẹni pupọ kú, melomelo li ore-ọfẹ Ọlọrun, ati ẹ̀bun ninu ore-ọfẹ ọkunrin kan, Jesu Kristi, di pupọ fun ẹni pupọ.

### I Peteru 5:5b
. . . nitori Ọlọrun kọ oju ija si awọn agberaga, ṣugbọn O nfi ore-ọfẹ fun awọn onirẹlẹ.

### Titu 3:7
Ki a le dá wa lare nipa ore-ọfẹ rẹ, ki a si le sọ wa di ajogún gẹgẹ bi ireti ìye ainipẹkun.

### Iṣe 4:33
Agbara nla li awọn aposteli si fi njẹri ajinde Jesu Oluwa; ore-ọfẹ pipọ si wà lori gbogbo wọn.

**Iṣe 3:19**

Nitorina ẹ ronupiwada, ki ẹ si tun yipada, ki a le pa ẹ̀ṣẹ nyin rẹ́, ki akoko itura ba le ti iwaju Oluwa wá.

**Iṣe 2:38**

Peteru si wi fun wọn pe, Ẹ ronupiwada, ki a si baptisi olukuluku nyin li orukọ Jesu Kristi fun idariji ẹ̀ṣẹ nyin, ẹnyin o si gbà ẹ̀bun Ẹmi Mimọ́.

**Matteu 3:2**

O si nwipe, Ẹ ronupiwada; nitori ijọba ọrun kù si dẹ̀dẹ̀.

**II Korinti 7:10**

Nitoripe ibanujẹ ẹni ìwa-bi-Ọlọrun a ma ṣiṣẹ ironupiwada si igbala ti kì mu abamọ wá: ṣugbọn ibanujẹ ti aiye a ma ṣiṣẹ ikú.

**Iṣe 17:30**

Igba aimọ̀ yi li Ọlọrun ti gboju fò da; ṣugbọn nisisiyi o paṣẹ fun gbogbo enia nibi gbogbo lati ronupiwada.

**Owe 28:13**

Ẹniti o bo ẹ̀ṣẹ rẹ̀ mọlẹ kì yio ṣe rere: Ṣugbọn ẹnikẹni ti o jẹwọ ti o si kọ̀ ọ silẹ yio ri ãnu.

**Luku 13:3**

Mo wi fun nyin, Bẹ̃kọ: bikoṣepe ẹnyin ronupiwada, gbogbo nyin ni yio ṣegbé bẹ̃ gẹgẹ.

### Iṣe 5:31

On li Ọlọrun fi ọwọ́ ọtún rẹ̀ gbéga lati jẹ Ọmọ alade ati Olugbala, lati fi ironupiwada fun Israeli, ati idariji ẹ̀ṣẹ.

### Esekieli 18:21

Ṣugbọn bi enia buburu yio ba yipada kuro ninu gbogbo ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o ti da, ti o si pa gbogbo aṣẹ mi mọ, ti o si ṣe eyi ti o tọ́, ati eyiti o yẹ, yiyè ni yio yè, on kì yio kú.

### Marku 2:5

Nigbati Jesu ri igbagbọ́ wọn o wi fun ẹlẹgba na pe, Ọmọ, a dari ẹ̀ṣẹ rẹ jì ọ.

### Isaiah 55:7

Jẹ ki enia buburu kọ̀ ọ̀na rẹ̀ silẹ ki ẹ̀lẹṣẹ si kọ̀ ironu rẹ̀ silẹ: si jẹ ki o yipada sị Oluwa, on o si ṣãnu fun u, ati si Ọlọrun wa, yio si fi jì li ọpọlọpọ.

### Ifihàn 3:20

Kiyesi i, mo duro li ẹnu ilẹkun, mo si nkànkun, bi ẹnikẹni ba gbọ́ ohùn mi, ti o si ṣí ilẹkun, emi o si wọle tọ̀ ọ wá, emi o si ma ba a jẹun, ati on pẹlu mi.

### Mattteu 6:14

Nitori bi ẹnyin ba fi ẹ̀ṣẹ awọn enia jì wọn, Baba nyin ti mbẹ li ọrun yio fi ẹ̀ṣẹ ti nyin jì nyin.

Kolosse 3:2

Ẹ mã ronu awọn nkan ti mbẹ loke kì iṣe awọn nkan ti mbẹ li aiye.

Titu 2:11, 12

Nitori ore-ọfẹ Ọlọrun ti nmu igbala fun gbogbo enia wá ti farahan, o nkọ́ wa pe, ki a sẹ́ aiwa-bi-Ọlọrun ati ifẹkufẹ aiye ki a si mã wà li airekọja, li ododo, ati ni ìwa-bi-Ọlọrun ni aiye isisiyi.

I Johannu 2:15, 16

Ẹ máṣe fẹran aiye, tabi ohun ti mbẹ ninu aiye. Bi ẹnikẹni ba fẹran aiye, ifẹ ti Baba kò si ninu rè. Nitori ohun gbogbo ti mbẹ li aiye, ifẹkufẹ ara, ati ifẹkufẹ oju, ati irera aiye, ki iṣe ti Baba, bikoṣe ti aiye.

Isaiah 1:16

Ẹ wẹ̀, ki ẹ mọ́; mu buburu iṣe nyin kuro niwaju oju mi: dawọ duro lati ṣe buburu.

Efesu 5:11

Ẹ má si ba aileso iṣẹ òkunkun kẹgbẹ pọ̀, ṣugbọn ẹ kuku mã ba wọn wi.

II Timoteu 4:10

Nitori Dema ti kọ̀ mi silẹ, nitori o nfẹ aiye isisiyi, o si lọ si Tessalonika; Kreskeni si Galatia, Titu si Dalmatia.

**Johannu 3:3**

Jesu dahùn o si wi fun u pe, Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun ọ, Bikoṣepe a tún enia bi, on kò le ri ijọba Ọlọrun.

**II Korinti 5:17**

Nitorina bi ẹnikẹni ba wà ninu Kristi, o di ẹda titun: ohun atijọ ti kọja lọ: kiyesi i, nwọn si di titun.

**I Johannu 2:29**

Bi ẹnyin ba mọ̀ pe olododo ni on, ẹ mọ̀ pe a bí olukuluku ẹniti nṣe ododo nipa rẹ̀.

**Esekieli 36:26**

Emi o fi ọkàn titun fun nyin pẹlu, ẹmi titun li emi o fi sinu nyin, emi o si mu ọkàn okuta kuro lara nyin, emi o si fi ọkàn ẹran fun nyin.

**I Johannu 5:18**

Awa mọ̀ pe ẹnikẹni ti a bí nipa ti Ọlọrun kì idẹṣẹ: ṣugbọn ẹniti a bí nipa ti Ọlọrun a mã pa ara rẹ̀ mọ́, ẹni buburu nì ki si ifọwọ́kàn a.

**Johannu 10:10**

Olè kì iwá bikoṣe lati jale, ati lati pa, ati lati parun: emi wá ki nwọn le ni ìye, ani ki nwọn le ni i lọpọlọpọ.

**I Peteru 1:23**

Bi a ti tun nyin bi, kì iṣe lati inu irú ti idibajẹ wá, bikoṣe eyiti ki idibajẹ nipa ọ̀rọ Ọlọrun ti mbẹ lãye ti o si duro.

**Efesu 2:1, 6**

Ẹnyin li o si ti sọ di àye, nigbati ẹnyin ti kú nitori irekọja ati èṣẹ nyin. . . O si ti ji wa dide pẹlu rẹ̀, o si ti mu wa joko pẹlu rẹ̀ ninu awọn ọrun ninu Kristi Jesu.

**Galatia 5:24**

Awọn ti iṣe ti Kristi Jesu ti kàn ara mọ agbelebu ti on ti ifẹ ati ifẹkufẹ rẹ̀.

**Romu 6:2, 11**

Awa ẹniti o ti kú si ẹ̀ṣẹ, awa o ha ṣe wà lãye ninu rẹ̀ mọ́? . . . Bẽni ki ẹnyin pẹlu kà ara nyin bi okú si ẹ̀ṣẹ, ṣugbọn bi alãye si Ọlọrun ninu Kristi Jesu.

**Kolosse 2:13**

Ati ẹnyin, ẹniti o ti kú nitori ẹ̀ṣẹ nyin ati aikọla ara nyin, mọ ni, ẹnyin li o si ti sọdi ãye pọ̀ pẹlu rẹ̀, o si ti dari gbogbo ẹ̀ṣẹ nyin jì nyin.

**I Peteru 2:24**

Ẹniti on tikararẹ̀ fi ara rẹ̀ rù ẹ̀ṣẹ wa lori igi, pe ki awa ki o le di okú si ẹ̀ṣẹ ki a si di ãye si ododo: nipa ìnà ẹniti a mu nyin larada.

**Kolosse 3:1**

Njẹ bi a ba ti ji nyin dide pẹlu Kristi ẹ mã ṣafẹri awọn nkan ti mbẹ loke, nibiti Kristi gbé wà ti o joko li ọwọ́ ọtun Ọlọrun.

## Johannu 17:3

Iye ainipẹkun na si li eyi, ki nwọn ki o le mọ̀ ọ, iwọ nikan Ọlọrun otitọ, ati Jesu Kristi, ẹniti iwọ rán.

## Johannu 3:36

Ẹniti o ba gbà Ọmọ gbọ́, o ni iye ainipẹkun: ẹniti kò ba si gbà Ọmọ, gbọ, kì yio ri ìye; ṣugbọn ibinu Ọlọrun mbẹ lori rẹ̀.

## Johannu 5:24

Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Ẹnikẹni ti o ba gbọ́ ọ̀rọ mi, ti o ba si gbà ẹniti o rán mi gbọ́, o ni iye ti kò nipẹkun, on kì yio si wá si idajọ; ṣugbọn a ti ré ikú kọja bọ si ìye.

## Romu 6:23

Nitori ikú li ère ẹ̀ṣẹ; ṣugbọn ẹ̀bun ọfẹ Ọlọrun ni ìye ti kò nipẹkun, ninu Kristi Jesu Oluwa wa.

## Johannu 3:14, 15

Bi Mose si ti gbé ejò soke li aginjù, gẹgẹ bẽli a kò le ṣe alaigbé Ọmọ-enia soke pẹlu; ki ẹnikẹni ti o ba gba a gbọ, ki o má ba ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni ìye ainipẹkun.

## Galatia 6:8

Nitori ẹniti o ba nfunrugbin sipa ti ara rẹ̀, nipa ti ara ni yio ká idibajẹ; sugbọn ẹniti o ba nfunrugbin sipa ti Ẹmí, nipa ti Ẹmí ni yio ká ìye ainipẹkun.

**Romu 8:16**

Ẹmí tikararẹ li o mba ẹmí wa jẹrí pe, ọmọ Ọlọrun li awa iṣe.

**Isaiah 32:17**

Iṣẹ ododo yio si jẹ alafia, ati eso ododo yio jẹ idakẹjẹ on ãbo titi lai.

**Galatia 4:6**

Ati nitoriti ẹnyin nṣe ọmọ, Ọlọrun si ti rán Ẹmí Ọmọ rẹ wá sinu ọkàn nyin, ti nke pe, Abba, Baba.

**Johannu 14:21**

Ẹniti o ba li ofin mi, ti o ba si npa wọn mọ́, on li ẹniti o fẹràn mi: ẹniti o ba si fẹràn mi, a o fẹràn rẹ lati ọdọ Baba mi wá, emi o si fẹràn rẹ, emi o si fi ara mi hàn fun u.

**I Johannu 3:18, 19, 24**

Ẹnyin ọmọ mi, ẹ máṣe jẹ ki a fi ọrọ ẹnu tabi ahọn fẹran, bikoṣe ni iṣe ati li otitọ. Ati nipa eyi li awa ó mọ pe awa jẹ ti otitọ, ati pe awa o si dá ara wa loju niwaju rẹ. . . Ẹniti o ba si pa ofin rẹ mọ́ ngbé inu rẹ, ati on ninu rẹ. Ati nipa eyi li awa mọ pe o ngbẽ inu wa, nipa Ẹmí ti o fifun wa.

**I Johannu 4:13**

Nipa eyi li awa mọ pe awa ngbé inu rẹ, ati on ninu wa, nitoriti o ti fi Ẹmí rẹ fun wa.

### Isaiah 12:3

Ẹnyin o si fi ayọ̀ fà omi jade lati inu kanga igbala wá.

### Orin 16:11

Iwọ o fi ipa ọ̀na ìye hàn mi; Ni iwaju rẹ li ẹkún ayọ̀ wà: Li ọwọ ọtún rẹ ni didùn-inu wà lailai.

### Efesu 3:17

Ki Kristi ki o le mã gbé inu ọkàn nyin nipa igbagbọ; pe bi ẹ ti nfi gbongbo mulẹ, ti ẹ si nfi ẹsẹ mulẹ ninu ifẹ.

### Galatia 2:20

A ti kàn mi mọ agbelebu pẹlu Kristi: ṣugbọn mo wà lãye, sibẹ ki iṣe emi mọ́, ṣugbọn Kristi wà lãye ninu mi: wiwà ti mo si wà lãye ninu ara, mo wa lãye ninu igbagbọ Ọmọ Ọlọrun, ẹniti o fẹ mi, ti o si fi on tikararẹ̀ fun mi.

### Johannu 17:13

Ṣugbọn nisisiyi emi si mbọ̀ wá sọdọ rẹ, nkan wọnyi ni mo si nsọ li aiye, ki nwọn ki o le ni ayọ̀ mi ni kikun ninu awọn tikarawọn.

### Johannu 15:11

Nkan wọnyi ni mo ti sọ fun nyin, ki ayọ̀ mi ki o le wà ninu nyin, ati ki ayọ̀ nyin ki o le kún.

### Romu 14:17

Nitori ijọba Ọlọrun kì iṣe jijẹ ati mimu; bikoṣe ododo, ati alafia, ati ayọ̀ ninu Ẹmí Mimọ́.

### Romu 6:16

Ẹnyin kò mọ̀ pe, ẹniti ẹnyin ba jọwọ ara nyin lọwọ fun bi ẹrú lati mã gbọ́ tirẹ̀, ẹrú ẹniti ẹnyin ba gbọ tirẹ̀ li ẹnyin iṣe; ibãṣe ti ẹ̀ṣẹ sinu ikú, tabi ti igbọran si ododo?

### I Samueli 12:15

Ṣugbọn bi ẹnyin ko ba gbà ohun Oluwa gbọ́, ti ẹ ba si tàpá si ọ̀rọ Oluwa, ọwọ́ Oluwa yio wà lara nyin ni ibi, bi o ti wà lara baba nyin.

### II Tessalonika 1:7-9

Ati fun ẹnyin, ti a npọ́n loju, isimi pẹlu wa, nigba ifarahàn Jesu Oluwa lati ọrun wá ninu ọwọ́ ina pẹlu awọn angẹli alagbara rẹ̀, ẹniti yio san ẹsan fun awọn ti kò mọ Ọlọrun ti nwọn si ṣe aigbọran si ihinrere Jesu Oluwa: awọn ẹniti yio jiya iparun ainipẹkun lati iwaju Oluwa wá, ati lati inu ogo agbara rẹ̀.

### Romu 2:13

Nitori kì iṣe awọn olugbọ ofin li alare lọdọ Ọlọrun, ṣugbọn awọn oluṣe ofin li a o dalare.

### Deuteronomi 11:26-28a

Wò o, emi fi ibukún ati egún siwaju nyin li oni; ibukún, bi ẹnyin ba gbà ofin OLUWA Ọlọrun nyin gbọ́, ti mo palaṣẹ fun nyin li oni: ati egún, bi ẹnyin kò ba gbà ofin OLUWA Ọlọrun. . .

### Filippi 2:11

Ati pe ki gbogbo ahọn ki o mã jẹwọ pe, Jesu Kristi ni Oluwa, fun ogo Ọlọrun Baba.

### I Johannu 2:23

Ẹnikẹni ti o ba sẹ́ Ọmọ, on na ni kò gbà Baba: ṣugbọn ẹniti o ba jẹwọ Ọmọ, o gbà Baba pẹlu.

### Luku 9:26

Nitori ẹnikẹni ti o ba tiju mi, ati ọ̀rọ mi, oju rẹ̀ li Ọmọ-enia yio si tì, nigbati o ba de inu ogo tirẹ̀, ati ti baba rẹ̀, ati ti awọn angẹli mimọ́.

### Matteu 10:32, 33

Nitorina ẹnikẹni ti o ba jẹwọ mi niwaju enia, on li emi o jẹwọ pẹlu niwaju Baba mi ti mbẹ li ọrun. Ṣugbọn bi ẹnikan ba si sẹ mi niwaju enia on na li emi o sẹ pẹlu niwaju Baba mi ti mbẹ li ọrun.

### II Timoteu 2:11, 12

Otitọ li ọrọ na: Nitoripe bi awa ba bá a kú, awa ó si bá a yè: bi awa ba farada, awa ó si ba a jọba: bi awa ba sẹ́ ẹ, on na yio si sẹ́ wa.

### Romu 10:9, 10

Pe, bi iwọ ba fi ẹnu rẹ jẹwọ Jesu li Oluwa, ti iwọ si gbagbọ́ li ọkàn rẹ pe, Ọlọrun jí i dide kuro ninu okú, a o gbà ọ là. Nitori ọkàn li a fi igbagbọ́ si ododo; ẹnu li a si fi ijẹwọ si igbala.

II Tessalonika 2:9

Ani on, ẹniti wíwa rẹ̀ yio ri gẹgẹ bi iṣẹ Satani pẹlu agbara gbogbo, ati àmi ati iṣẹ-iyanu eke.

Efesu 6:11

Ẹ gbe gbogbo ihamọra Ọlọrun wọ̀, ki ẹnyin ki o le kọ oju ija si arekereke Eṣu.

Matteu 4:1, 10, 11

Nigbana li a dari Jesu si ijù lati ọwọ́ Ẹmi lati dán a wò lọwọ Èṣu. . . Nigbana ni Jesu wi fun u pe, Pada kuro lẹhin mi, Satani: nitori a kọwe rè pe, Oluwa Ọlọrun rẹ ni ki iwọ ki o foribalẹ fun, on nikanṣoṣo ni ki iwọ mã sìn. Nigbana li Èṣu fi i silẹ lọ; si kiyesi i, awọn angẹli tọ̀ ọ wá, nwọn si nṣe iranṣẹ fun u.

Iṣe 26:18

Lati là wọn li oju, ki nwọn ki o le yipada kuro ninu òkunkun si imọlẹ, ati kuro lọwọ agbara Satani si Ọlọrun, ki nwọn ki o le gbà idariji ẹṣẹ, ati ogún pẹlu awọn ti a sọ di mimọ́ nipa igbagbọ ninu mi.

I Peteru 5:8

Ẹ mã wà li airekọja, ẹ mã ṣọra; nitori Èṣu, ọtá nyin, bi kiniun ti nke ramuramu, o nrìn kãkiri, o nwá ẹniti yio pajẹ kiri.

### II Tessalonika 2:8

Nigbana li a ó si fi ẹni ẹṣẹ nì hàn, ẹniti Oluwa yio fi ẽmi ẹnu rẹ̀ pa, ti yio si fi ifihan wíwa rẹ̀ sọ di asan.

### I Johannu 3:8

Ẹniti o ba ndẹṣẹ ti Èṣu ni; nitori lati àtetekọṣe ni Èṣu ti ndẹṣẹ. Nitori eyi li Ọmọ Ọlọrun ṣe farahàn, ki o le pa iṣẹ Èṣu run.

### Romu 8:35, 37

Tani yio ha yà wa kuro ninu ifẹ Kristi? ipọnju ni, tabi wahalà, tabi inunibini, tabi ìyan, tabi ìhoho, tabi ewu, tabi idà? . . . Ṣugbọn ninu gbogbo nkan wọnyi awa jù ẹniti o ṣẹgun lọ nipa ẹniti o fẹ wa.

### Jakọbu 4:7-8a

Nitorina ẹ tẹriba fun Ọlọrun. Ẹ kọ oju ija si Eṣu, on ó si sá kuro lọdọ nyin. Ẹ sunmọ Ọlọrun, on o si sunmọ nyin.

### II Korinti 10:4

Nitori ohun ija wa kì iṣe ti ara, ṣugbọn o li agbara ninu Ọlọrun lati wó ibi giga palẹ.

### Heberu 2:14

Njẹ niwọn bi awọn ọmọ ti ṣe alabapin ara on ẹ̀jẹ, bẽ gẹgẹ li on pẹlu si ṣe alabapin ninu ọkanna; ki o le ti ipa ikú pa ẹniti o ni agbara ikú rum, eyini ni Eṣu.

I Korinti 13:1

Bi mo tilẹ nfọ oniruru ede ati ti angẹli, ti emi kò si ni ifẹ, emi dabi idẹ ti ndún, tabi bi simbali olohùn goro.

I Johannu 3:14

Awa mọ̀ pe awá ti rekọja lati inu ikú sinu ìye, nitoriti awa fẹràn awọn ará. Ẹniti kò ba ni ifẹ o ngbé inu ikú.

Galatia 5:22, 23a

Ṣugbọn eso ti Ẹmí ni ifẹ, ayọ̀, alafia, ipamọra, ìwa pẹlẹ, iṣore, igbagbọ́, Ìwa tutù, ati íkora-ẹni-nijanu. . .

I Johannu 4:20

Bi ẹnikẹni ba wipe, Emi fẹran Ọlọrun, ti o si korira arakunrin rè, eke ni: nitori ẹniti kò fẹran arakunrin rẹ ti o ri, bawo ni yio ti ṣe le fẹran Ọlọrun ti on kò ri?

Johannu 13:35

Nipa eyi ni gbogbo enia yio fi mọ̀ pe, ọmọ ẹhin mi li ẹnyin iṣe, nigbati ẹnyin ba ni ifẹ si ọmọnikeji nyin.

I Johannu 5:3a

Nitori eyi ni ifẹ Ọlọrun, pe ki awa ki o pa ofin rẹ mọ́. . .

Johannu 21:16

O tún wi fun u nigba keji pe, Simoni ọmọ Jona iwọ fẹ mi bi? O wi fun u pe, Bẹ̃ni Oluwa; iwọ mọ̀ pe, mo fẹràn rẹ. O wi fun u pe, Mã bọ́ awọn agutan mi.

## Romu 4:25

Ẹniti a fi tọrẹ nitori ẹ̀ṣẹ wa, ti a si jinde nitori idalare wa.

## Johannu 20:26-28

Lẹhin ijọ mẹjọ awọn ọmọẹhin si tún wà ninu ile, ati Tomasi pẹlu wọn: nigbati a si ti tì ilẹkun, Jesu de, o si duro larin, o si wipe, Alafia fun nyin. Nigbana li o wi fun Tomasi pe, Mu ika rẹ wá nihin, ki o si wò ọwọ́ mi; si mu ọwọ́ rẹ wá nihin, ki o si fi si ìha mi: kì iwọ ki o máṣe alaigbagbọ́ mọ́, ṣugbọn jẹ onigbagbọ. Tomasi dahun o si wi fun u pe, Oluwa mi ati Ọlọrun mi!

## Marku 16:9

Nigbati Jesu jinde li owurọ̀ kutukutu ni ijọ kini ọ̀sẹ, o kọ́ fi ara hàn fun Maria Magdalene, lara ẹniti o ti lé ẹmi ẹ̀ṣu meje jade.

## Iṣe 10:39-41

Awa si li ẹlẹri gbogbo ohun ti o ṣe, ni ilẹ awọn Ju, ati ni Jerusalemu; ẹniti nwọn pa, ti nwọn si fi gbékọ sori igi: on li Ọlọrun jinde ni ijọ kẹta, o si fi i hàn gbangba: kì iṣe fun gbogbo enia, bikoṣe fun awọn ẹlẹri ti a ti ọwọ Ọlọrun yàn tẹlẹ, fun awa, ti a ba a jẹ, ti a si ba a mu lẹhin igbati o jinde kuro ninu okú.

**Matteu 16:21**

Lati igbana lọ ni Jesu ti bẹrẹ si ifihàn awọn ọmọ-ẹhin rẹ, bi on ko ti le ṣailọ si Jerusalemu, lati jẹ ọpọ ìya lọwọ awọn àgbã-gbà ati awọn olori alufa, ati awọn akọwe, ki a si pa on, ati ni ijọ kẹta, ki o si jinde.

**Johannu 5:25, 28, 29**

Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Wakati na mbọ, o si de tan nisisiyi, nigbati awọn okú yio gbọ ohùn Ọmọ Ọlọrun: awọn ti o ba gbọ yio si yè. . . Ki eyi ki o máṣe yà nyin li ẹnu; nitoripe wakati mbọ, ninu eyiti gbogbo awọn ti o wà ni isà okú yio gbọ ohùn rẹ. Nwọn o si jade wá; awọn ti o ṣe rere, si ajinde ìye; awọn ti o si ṣe buburu, si ajinde idajọ.

**Romu 6:3-5**

Tabi ẹ kò mọ pe, gbogbo wa ti a ti baptisi sinu Kristi Jesu, a ti baptisi wa sinu ikú rẹ? Njẹ a fi baptismu sinu ikú sin wa pọ pẹlu rẹ: pe gẹgẹ bi a ti jí Kristi dide kuro ninu okú nipa ogo Baba, bẹ̃ni ki awa pẹlu ki o mã rìn li ọtun ìwa. Nitori bi a ba ti so wa pọ pẹlu rẹ nipa afarawe ikú rẹ, a o si so wa pọ pẹlu nipa afarawe ajinde rẹ.

## II Timoteu 2:21

Bi ẹnikẹni ba wẹ̀ ara rẹ̀ mọ́ kuro ninu wọnyi, on ó jẹ ohun èlo si ọlá, ti a yà si ọ̀tọ, ti o si yẹ fun ìlo bãle, ti a si ti pèse silẹ si iṣẹ rere gbogbo.

## Matteu 3:11

Lõtọ li emi nfi omi baptisi nyin fun ironupiwada: ṣugbọn ẹnikan ti o pọ̀ju mi lọ mbọ̀ lẹhin mi, bàta ẹniti emi ko to gbé; on ni yio fi Ẹmí Mimọ́ ati iná baptisi nyin.

## I Peteru 1:15

Ṣugbọn gẹgẹ bi Eni ti o pè nyin ti jẹ mimọ́, bẽni ki ẹnyin na si jẹ mimọ́ ninu ìwa nyin gbogbo.

## Luku 1:74, 75

Pe on o fifun wa, lati gbà wa lọwọ awọn ọtá wa, Ki awa ki o le ma sìn i laifòya, Ni mimọ́ ìwa ati li ododo niwaju rẹ, li ọjọ aiye wa gbogbo.

## II Timoteu 2:15

Ṣãpọn lati fi ara rẹ hàn niwaju Ọlọrun li ẹniti o yẹ́jẹ́, aṣiṣẹ ti kò ni lati tiju, ti o npín ọ̀rọ otitọ bi o ti yẹ.

## II Korinti 7:1

Nitorina, ẹnyin olufẹ, bi a ti ni ileri wọnyi, ẹ jẹ ki a wẹ̀ ara wa mọ́ kuro ninu gbogbo ẹgbin ti ara ati ti ẹmí, ki a mã sọ ìwa mimọ́ di pipé ni ìbẹru Ọlọrun.

### Efesu 4:24

Ki ẹ si gbe ọkunrin titun nì wọ̀, eyiti a da nipa ti Ọlọrun li ododo ati li iwa mimọ́ otitọ́.

### Heberu 13:12

Nitorina Jesu pẹlu, ki o le fi ẹ̀jẹ ara rẹ̀ sọ awọn enia di mimọ́, o jìya lẹhin bode.

### I Johannu 1:9

Bi awa ba jẹwọ ẹ̀ṣẹ wa, olõtọ ati olododo li on lati dari ẹṣẹ wa jì wa, ati lati wẹ̀ wa nù kuro ninu aiṣododo gbogbo.

### Isaiah 35:8

Opopo kan yio si wà nibẹ, ati ọ̀na kan, a o si ma pè e ni, Ọ̀na iwà-mimọ́; alaimọ́ kì yio kọja nibẹ; nitori on o wà pẹlu wọn: awọn èro ọ̀na na, bi nwọn tilẹ jẹ òpe, nwọn ki yio ṣì i.

### I Peteru 1:2

Gẹgẹ bi ìmọtẹlẹ Ọlọrun Baba, nipa isọdimimọ́ Ẹmí, si igbọran ati ibuwọ́n ẹ̀jẹ Jesu Kristi: Ki ore-ọfẹ ati alafia ki o mã bi si i fun nyin.

### Efesu 1:4

Ani gẹgẹ bi o ti yàn wa ninu rẹ̀ ṣaju ipilẹṣẹ aiye, ki awa ki o le jẹ mimọ́ ati alailabùku niwaju rẹ̀ ninu ifẹ.

### II Peteru 3:11

Njẹ bi gbogbo nkan wọnyi yio ti yọ́ nì, irú enia wo li ẹnyin iba jẹ ninu ìwa mimọ́ gbogbo ati ìwa-bi-Ọlọrun.

### Iṣe 1:8a

Ṣugbọn ẹnyin ó gbà agbara, nigbati Ẹmí Mimọ́ ba bà le nyin: ẹ o si ma ṣi ẹlẹri mi. . .

### Iṣe 11:24

Nitori on jẹ enia rere, o si kún fun Ẹmí Mimọ́, ati fun igbagbọ́: enia pipọ li a si kà kún Oluwa.

### Luku 11:13

Njẹ bi ẹnyin ti iṣe enia buburu ba mọ̀ bi ãti ifi ẹ̀bun didara fun awọn ọmọ nyin: melomelo ni Baba nyin ti mbẹ li ọrun yio fi Ẹmí Mimọ́ rẹ̀ fun awọn ti o mbère lọdọ rẹ̀?

### Esekieli 36:27

Emi o si fi ẹmi mi sinu nyin, emi o si mu ki ẹ ma rìn ninu aṣẹ mi, ẹnyin o pa idajọ mi mọ, ẹ o si ma ṣe wọn.

### Iṣe 4:31

Nigbati nwọn gbadura tan, ibi ti nwọn gbé pejọ si mi titi; gbogbo wọn si kún fun Ẹmí Mimọ́, nwọn si nfi igboiya sọ ọ̀rọ Ọlọrun.

### Iṣe 13:52

Awọn ọmọ-ẹhin si kún fun ayọ̀ ati fun Ẹmi Mimọ́.

### Romu 8:9

Ṣugbọn ẹnyin kò si ninu ti ara, bikoṣe ninu ti Ẹmí, biobaṣepe Ẹmí Ọlọrun ngbe inu nyin. Ṣugbọn bi ẹnikẹni kò ba ni Ẹmí Kristi, on kò si ninu ẹni tirẹ̀.

# ILERI TI O YANILẸNU FUN AWON ONIGBAGBO

### Orin 37:3

Gbẹkẹle Oluwa, ki o si ma ṣe rere; Mã gbe ilẹ na, ki o si mã huwa otitọ.

### Isaiah 66:2

Nitori gbogbo nkan wọnni li ọwọ́ mi sa ti ṣe, gbogbo nkan wọnni si ti wà, li Oluwa wi: ṣugbọn eleyi li emi o wò, ani òtoṣi ati oniròbinujẹ ọkàn, ti o si nwarìri si ọ̀rọ mi.

### I Peteru 4:12, 13

Olufẹ, ẹ máṣe ka idanwò inà ti mbẹ larin nyin eyiti o de si nyin lati dan nyin wò bi ẹnipe ohun àjeji li o de bá nyin: Ṣugbọn niwọnbi ẹnyin ti jẹ alabapin ìya Kristi, ẹ mã yọ̀, ki ẹnyin ki o le yọ̀ ayọ̀ pipọ nigbati a ba fi ogo rẹ̀ hàn.

### Ifihàn 21:4

Ọlọrun yio si nù omije gbogbo nù kuro li oju wọn; kì yio si si ikú mọ́, tabi ọfọ, tabi ẹkún, bẽni ki yio si irora mọ́: nitoripe ohun atijọ ti kọja lọ.

### Heberu 12:7a

Ẹ mã mu suru labẹ ibawi: Ọlọrun mba nyin lo bi ọmọ ni. . .

### Orin 34:18

Oluwa mbẹ leti ọdọ awọn ti ise onirobinujẹ ọkàn; O si gbà iru awọn ti iṣe onirora ọkán là.

**Romu 8:28**

Awa si mọ̀ pe ohun gbogbo li o nṣiṣẹ pọ̀ si rere fun awọn ti o fẹ Ọlọrun, ani fun awọn ẹniti a pè gẹgẹ bi ipinnu rẹ̀.

**Heberu 2:18**

Nitori niwọnbi on tikararẹ̀ ti jiya nipa idanwo, o le ràn awọn ti a ndan wo lọwọ.

**Romu 16:20**

Ọlọrun alafia yio si tẹ̀ Satani mọlẹ li atẹlẹsẹ nyin ni lõlọ.

**I Korinti 10:13**

Kò si idanwò kan ti o ti ibá nyin, bikoṣe irú eyiti o mọ̀ niwọn fun enia: ṣugbọn olododo li Ọlọrun ẹniti kì yio jẹ ki a dan nyin wò jù bi ẹnyin ti le gbà; ṣugbọn ti yio si ṣe ọna atiyọ pẹlu ninu idanwò na, ki ẹnyin ki o ba le gbà a.

**Orin 34:19**

Ọpọlọpọ ni iponju olododo; Ṣugbọn Oluwa gbà a ninu wọn gbogbo.

**II Korinti 4:17**

Nitori iponju wa ti o fẹrẹ, ti iṣe fun iṣẹju kan, o nṣiṣẹ ogo ainipẹkun ti o pọ̀ rekọja fun wa.

**Isaiah 43:2**

Nigbati iwọ ba nlà omi kọja, emi o pẹlu rẹ; ati lãrin odò, nwọn ki yio bò ọ mọlẹ: nigbati iwọ ba nrìn ninu iná, ki yio jo ọ, bẹ̃ni ọwọ́-iná ki yio ràn ọ.

**Ifihàn 3:5**

Ẹniti o ba ṣẹgun, on na li a o fi aṣọ funfun wọ̀; emi kì yio pa orukọ rẹ̀ ré kuro ninu iwe ìye, ṣugbọn emi o jẹwọ orukọ rẹ̀ niwaju Baba mi, ati niwaju awọn angẹli rẹ̀.

**Ifihàn 2:7**

Ẹniti o ba li eti ki o gbọ́ ohun ti Ẹmí nsọ fun awọn ijọ. Ẹniti o ba ṣẹgun ni emi o fi eso igi ìye nì fun jẹ, ti mbẹ larin Paradise Ọlọrun.

**Ifihàn 3:12**

Ẹniti o ba ṣẹgun, on li emi o fi ṣe ọwọ̀n ninu tẹmpili Ọlọrun mi, on kì yio si jade kuro nibẹ mọ́: emi o si kọ orukọ Ọlọrun mi si i lara, ati orukọ ilu Ọlọrun mi, ti iṣe Jerusalemu titun, ti o nti ọrun sọkalẹ lati ọdọ Ọlọrun mi wá, ati orukọ titun ti emi tikarami.

**Ifihàn 3:21**

Ẹniti o ba ṣẹgun li emi o fifun lati joko pẹlu mi lori itẹ́ mi, bi emi pẹlu ti ṣẹgun, ti mo si joko pẹlu Baba mi lori itẹ́ rẹ̀.

**Ifihàn 2:26**

Ẹniti o ba si ṣẹgun, ati ẹniti o ba pa iṣẹ mi mọ́ titi de opin, emi o fun u li aṣẹ lori awọn orilẹ-ède.

**Ifihàn 21:7**

Ẹniti o ba ṣẹgun ni yio jogún nkan wọnyi: emi o si mã jẹ Ọlọrun rẹ̀, on o si mã jẹ ọmọ mi.

# ỌRỌ ỌLỌRUN NIPA IKỌSILẸ LARIN TỌKỌ TAYA

## Luku 16:18

Ẹnikẹni ti o ba kọ̀ aya rẹ̀ silẹ, ti o si gbé omiran ni iyawo, o ṣe panṣaga: ẹnikẹni ti o ba si gbé, ẹniti ọkọ rẹ̀ kọ̀ silẹ ni iyawo, o ṣe panṣaga.

## Romu 7:2, 3

Nitori obinrin — ti o ni ọkọ, ìwọn igbati ọkọ na wà lãye, a fi ofin dè e mọ́ ọkọ na; ṣugbọn bi ọkọ na ba kú, a tú u silẹ kuro ninu ofin ọkọ na.

## I Korinti 7:10, 11, 39

Ṣugbọn awọn ti o ti gbeyawo ni mo si paṣẹ fun, ṣugbọn kì iṣe emi, bikoṣe Oluwa, Ki aya máṣe fi ọkọ rẹ̀ silẹ. Ṣugbọn bi o bá si fi i silẹ, ki o wà li ailọkọ, tabi ki o ba ọkọ rẹ̀ làja: ki ọkọ ki o máṣe kọ̀ aya rẹ̀ silẹ. . . A fi ofin dè obinrin niwọn igbati ọkọ rẹ̀ ba wà lãye; ṣugbọn bi ọkọ rẹ̀ ba kú, o di omnira lati ba ẹnikẹni ti o wù u gbeyawo; kìki ninu Oluwa.

## Matteu 5:32

Ṣugbọn emi wi fun nyin, Ẹnikẹni ti o ba kọ̀ aya rẹ̀ silẹ, bikoṣe nitori àgbere, o mu u ṣe panṣaga; ẹnikẹni ti o ba si gbé ẹniti a kọ̀ silẹ ni iyawo, o ṣe panṣaga.

### Matteu 24:27

Nitori gẹgẹ bi manamana ti ikọ lati ila-õrun, ti isi mọlẹ de ìwọ-õrun; bẽni wiwa Ọmọ-enia yio ri pẹlu.

### Matteu 24:30

Nigbana li àmi Ọmọ-enia yio si fi ara hàn li ọrun; nigbana ni gbogbo ẹya aiye yio kãnu, nwọn o si ri Ọmọ-enia ti yio ma ti oju ọrun bọ̀ ti on ti agbara ati ogo nla.

### Marku 8:38

Nitori ẹnikẹni ti o ba tiju mi, ati ọ̀rọ mi, ni iran panṣaga ati ẹlẹṣẹ yi, on na pẹlu li Ọmọ-enia yio tiju rẹ̀, nigbati o ba de ninu ogo Baba rẹ̀ pẹlu awọn angẹli mimọ́.

### Johannu 14:3

Bi mo ba si lọ ipèse àye silẹ fun nyin, emi o tún pada wá, emi o si mu nyin lọ sọdọ emi tikarami; pe nibiti emi gbé wà, ki ẹnyin le wà nibẹ pẹlu.

### Jakọbu 5:8

Ẹnyin pẹlu ẹ mu sũru; ẹ fi ọkàn nyin balẹ̀: nitori ipadawa Oluwa kù si dẹdẹ.

### Ifihàn 3:11

Kiyesi i, emi mbọ̀ nisisiyi: di eyiti iwọ ni mu ṣinsin, ki ẹnikẹni ki o máṣe gbà ade rẹ.

**I Johannu 3:2**

Olufẹ, ọmọ Ọlọrun li awa iṣe nisisiyi, a kò si ti ifihàn bi awa ó ti ri: awa mọ pe, nigbati o ba farạ han, a ó dabi rẹ; nitori awa o ri i ani bi on ti ri.

**Heberu 9:28**

Bẽni Kristi pẹlu lẹhin ti a ti fi rubọ lẽkanṣoṣo lati ru ẹṣẹ ọpọlọpọ, yio farahan nigbakeji laisi ẹṣẹ fun awọn ti nwo ọna rẹ fun igbala.

**Luku 12:40**

Nitorina ki ẹnyin ki o mura pẹlu: nitori Ọmọ-enia mbọ ni wakati ti ẹnyin kò daba.

**Iṣe 1:11**

Ti nwọn si wipe, Ẹnyin ará Galili, ẽṣe ti ẹ fi duro ti ẹ nwò oju ọrun? Jesu na yi, ti a gbà soke ọrun kuro lọwọ nyin, yio pada bẽ gẹgẹ bi ẹ ti ri i ti o nlọ si ọrun.

**Luku 21:27**

Nigbana ni nwọn o si ri Ọmọenia ti yio ma bọ ninu awọsanma ti on ti agbara ati ogo nla.

**Matteu 16:27**

Nitori Ọmọ-enia yio wá ninu ogo Baba rẹ pẹlu awọn angẹli rẹ; nigbana ni yio san a fun olukuluku gẹgẹ bi iṣẹ rẹ.

# ỌRỌ ỌLỌRUN

**Orin 119:105**
Ọ̀rọ rẹ ni fitila si mi li ẹsẹ,
Ati imọlẹ si ipa ọ̀na mi.

**Orin 119:11**
Ọ̀rọ rẹ ni mo pamọ́ li ọkàn mi,
Ki emi ki o má ba ṣẹ̀ si ọ.

**Matteu 22:29**
Jesu dahùn o si wi fun wọn pe, Ẹnyin ṣìna, nitori ẹnyin kò mọ̀ iwe-mimọ́, ẹ kò si mọ̀ agbara Ọlọrun.

**II Peteru 1:21**
Nitori asọtẹlẹ kan kò ti ipa ifẹ enia wá ri; ṣugbọn awọn enia nsọrọ lati ọdọ Ọlọrun bi a ti ndari wọn lati ọwọ́ Ẹmí Mimọ́ wá.

**Luku 21:33**
Ọrun on aiye yio rekọja: ṣugbọn ọ̀rọ mi kì yio rekọja.

**Orin 119:89**
Ọluwa, lai, Ọ̀rọ rẹ kalẹ li ọrun.

**Deuteronomi 4:2**
Ẹ kò gbọdọ bu kún ọ̀rọ na ti mo palaṣẹ fun nyin, bẹ̃li ẹnyin kò gbọdọ bù kuro ninu rẹ̀, ki ẹnyin ki o le pa ofin OLUWA Ọlọrun nyin mọ́, ti mo palaṣẹ fun nyin.

**II Timoteu 3:16**
Gbogbo iwe-mimọ́ ti o ni imísi Ọlọrun li o si nì ère fun ẹkó, fun iba-ni-wi, fun itọ́ni, fun ikóni ti o wà ninu ododo.

Published in numerous languages by the World Missionary Press as God supplies funds in answer to prayer. If you would like more copies for careful distribution, write in English to:

World Missionary Press, Inc.
Box 120
New Paris, Indiana 46553 U.S.A.

Gbedde. Egba. Akono.

Text reprinted from the Bible in Yoruba by permission of the United Bible Societies Africa Regional Centre, Nairobi, Kenya.

Awori. Aworo.

Nigeria West Kabba. Ijesha. Bunu.

Kwara Borgu Iworro. Ila. Ekiti.

Oyo Ijebu. Ilaje.

Ilorin. Igbena. Ikale,

Ogun Yagba. Wo.

PRINTED IN U.S.A.

Kogi Owe.

Ondo Igbomena-Ekiti Jumu.



16M Lagos YOR